ELETI OFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 938 LAGOS SATURDAY SEPTEMBER 12 EPTEMBER 18 1964 KOBO MEJI (2D)

Oro Behin Yo!

# Onile Kan P'oku Orun Lejo Nitori Owo Ile Nilu Oyinbo

LONDON — Orişirişi awọn nkan ti ko şẹle ri ni siye awọn baba wa n a ngbọ ninu aiye ti a wa lode isinsiyi bi nkan abami ki enia bi ẹranko, bi ki ẹranko bi enia. Irohin a-gbọ-yanu kan ti o ta si wa leti ni ti iya onile mehaya kan ni ilu Oyinbo ti o pe Ologbe kan ti o haya ile lọwọ rẹ lati nkan bi ọdun kẹwa lẹjọ si kotu.

A gbọ wipe ojiji ni ẹniti o haya ile lọwọ iya onile na ku sinu iyara rẹ, lẹhin igbati awọn ọmọ rẹ sinku rẹ tan, nwọn ni awọn fẹ ko ẹru rẹ, iya onile kọ jalẹ, o ni on şe iwe adehun pe lu oku na. O ni nkan ti o wa ninu iwe na ni wipe Ologbe na ni lati fun on ni iwe oşu kan wipe ON FẸ FI ILE ON SILẸ, fifisilẹ ti Ologbe na fi ile on silẹ ni ojiji ko pe on rara.

Wara were o ti lọ si kotu lati pe oku na lẹjọ Rogbodiyan ọrọ ẹjọ na si wa ni iwaju adajọ kotu agbegbe ti ile na wa. O ni owo oşu kan gbako ni on yio gba lọwọ ologbe na.

---

AKIYESI: Ẹ ka ọrọ Olotu loju ewe kẹrin nipa OFIN MAJẸKAGBỌ ti Ijọba fẹ gbe jade pẹlu ọrọ ẸGBẸ IRE ILU EKO.

## Adajọ Ju "Ogboriefon" Sewọn N'Ibadan

IBADAN — Ọjọ buruku eşu gbomi mu ni ọjọ Aje to kọja je fun Adebayọ Alaa, dongari janduku ẹgbẹ ọlọpẹ kan ti nwọn npe adape oruko rẹ ni "Ogboriẹfọn" ni Ibadan nigb ti adajọ kotu awọn andu u. Ọgbẹni T.S. Gomez ni o lọ sẹwọn oşu mẹfa fun ẹiri ti awọn ọlọpa ri ida ori ibọn wọn lọwọ rẹ laipẹ yi.

Nigbati ọdaran na ma wi, o sọfun adajọ pe ọwọ ọrẹ on atun kẹkẹ basikulu şe kan ni on ti gba a, şugbọn on ko tun le mọ ibiti on na gbe mọ, şugbọn adajọ ko gba ọrọ rẹ gbọ, o ni otitọ ni Ogboriẹfọn jẹbi ẹsun na.

Idajọ yi ko dun mọ lọya rẹ Alhaji Ọbişẹsan ninu, o si sọ fun adajọ Gomez wipe awọn ngbe ẹjọ na lọ si kotu kotẹmilọrun.

## Oyinbo Kingsway Firu Fona l'Eko Lodo Alarede

EKO—Ọgbẹni John Adaleteh, ara ilu Togo ni agbegbe ilẹ awọn Faranse, to ngbe Surulere la gbọ pe o ja wọ inu ile itaja ti Kingsway lọ ni Ẹhingbẹti l'Eko lati foju kan Oyinbo ọga işẹ to wa nibẹ to njẹ Peter Chadwick ti nwọn ni o lu iyawo rẹ alarede ti o loyun sinu şugbọn nwọn kọ lati jẹki ọkunrin na wọle ki tulasi ma ba bẹ silẹ nitori pẹlu ibinu ni o mbọ fififi.

(Wo iyoku loju ewe kejọ)

LAGOS RACE CLUB

OCTOBER MEETING, 1964.

SUNDAYS 4TH, 11TH, 18TH, 25TH OCTOBER AND 1ST NOVEMBER, 1964.

Provisional Programme and Entry Forms can be obtained on application to the Secretary, P O Box 51, Lagos or at the Race Course, Lagos

Note — No entry fees will be refunded after the draw has been made.

Entries close at noon on Monday 14th September, 1964.

No Cheque will be accepted.

C. H. E MILLER
Hon. SECRETARY

# Nosi Kan Poko Re Lejo Nitori Iwa Agbere

EKO — Obinrin kan to nșișę nọọsi ni ile awọn alaisan ni E o ti oru ọ tę nję Mercy Nnenaya Odumody ni a gbọ wipe o ti pe ọkọ rę, Ọgbęni Peter Odumody ọga agba kan n le ișę awọn onipulu ni Eko lęjọ lati kọ ọkọ re na sile, adajọ kotu ganran ni Eko si ti fi gbigbọ ęjọ na si ipari oșu yi.

A gbọ pe lati ilu Oyinbo ni awọn mejeji ti fę ara wọn wa, nwọn si gbe ara wọn la'arede nibiti nwọn gbe ti nșe e t o igbeyawo alarede ni Essex ilu Oyinbo.

Gbara ti obinrin na ti gbe iwe ipęjọ yi kalę si kotu nwọn ti palșe fun pe ki o ma tę siwaju nipa ọrọ na. Obinrin na, ninu iwe ipęjọ to șe, o ni ọkọ on ba obinrin miran to tun ję a'e rę kan lo pọ nibi i awọn gbe ngbe lęhin ọjọ die ti awọn ti gbeyawo tan ni Lọndọn, ati pe igbakugba ni o ma n mu ale rę yi wa sinu ile ibiti awọn ngbe ni Suru-Lere, o si fęran lati ma gbe awọn obinrin lọ sori będi lọ ba'lo pọ ninu yara awọn.

Mercy iyawo alarede yi tun sọ siwaju ninu ọrọ rę pe ọkọ on ti ni ki on ko ęru on abe ki on ba ęsę sọrọ bi on ko ba ni ifarada tabi inu didun si ati ma ri awọn ale on.

Ni ipari ọrọ re ninu iwe ipęjọ na; o dahuu pe ni ọ o kejilelogun oșu kej ọdun yi, ip ni ọkọ on fi gbe on ju sita, o si tun fa- a e kori leti lọ si ibi ese n'a ka i ti awọn ębi on ti pese silę lati fi ki on ku abọ lati ilu oyinbo n i n u oșu kei ọdun yi, nwọn și nba ọrọ na lọ.

# Atejade Oruko Fun Ibo-Didi Ku Sidede

EKO—Ọgbę i E. E. Esua ti ijọba apapọse yan gęgębi olușeto nipa ijoko ninu ile igbimọ ijọba așofin lori ibo didi sọ ni Eko ni ọię Isęgun to koja wipe atejade orukọ awọn ti yio dibo ijọba apapọ t mbọ yi ko ti le jade titi di igbati ile igbimọ ba fi ọwọ si eto titun lori didin joko ile igbimọ ku eyiti ijọba ti yan fun lati șe.

Gęgębi ikede kan to jade n i n u ọ ș e to kọja, nwọn ni iwe awọn orukọ na ibi ti jade ni Eko fun gbog o enia lati ka f u n ọjọ męędogun pere lati ọjọ A j e to kọja șugbọn f u n idiwọ atako kan ti awọn ęgbę kan gbe jade pe nwọn ni'la i tęle ilana ofin ijọba lori eto didi i b o, o m u ki fasę die wa lati tę iwe n a jade.

Lori ọrọ yi Oloye Adeniran Ogunsanya to ję alaga igbimọ ajiroro fun ęgbę Al kuka ni Eko to tun șe așiwaju fun awọn ęgbę oselu par pọ kan ti nwọn npe ni UPGA lọ sibi ipa de eto s șe nipa ibo didi ti nwọn șe ni Eko ti pinnu lati gbe ọ r ọ na lọ si kotu, nitoripe ko tọ lati tę i w e na jade lai ję p e nwọn tęle ilana ofin idibo na.

Awọn olușet nip oru kọ idibo na ni gęgębi ilana ofin ęsę kokanle ladọta apa kęrin rę, lori ifęsęmu lele awọn y i o d a tite iwe na duro, nwọn si ti bęręs șe ipade aw kekere kan lati tun j i r o r o lori awọn nkan to așęlę lori didin ilu Eko k u sęhin.

Gęgębi a ti mọ pe akojọpọ iye awọn enia to ngbe ilu Eko ję okę mętalelọgbọn p ę l u ęgbęrindinlogbọn leladọta o din męrin (665,246) sibę na i j o k o męrin pere ni Eko ni ninu ile igbimọ așofin ijọba.

# Iyaafin Kuti Pe Awon Oyinbo Elepo L'ejo

EKO — Adajọ Kotu ganran l'Eko ti sun ọjọ ti wọn yio gbọ ęjọ kan t Iyaafin Funmilayọ Ransome-Kuti pe awọn oyinbo elepo moto kan, (Total Oil (Nigeri ) Ltd. ati Ọgbęni J.B. Atunrașe si iwaju lori ile re kan ti o wa ni Ojuelegba ni Suru-Lere nitori ara ọkan ninu awọn lọya wọn ti ko ya.

Ninu iwe ipęjọ Iyaafin Kuti ti fi pe awọn Oyinbo elepo na ni o fę gba ęgbęruu pọuun (£1,000) lọwọ awọn ti nwọn nlo ilę na, nitoripe nwọn ko gba așę lọwọ on onile rarę, lehinna ou gba idajọ lori rę gęgębi ęniti o ni ilę ati wipe ki odajọ ilọ fun wọn ki nwọn ma tun lo ilę na mọ.

A gbọ wipe nwọn yio ma ba riro ęjọ na lọ n ọjọ kęrin oșu kọkanla ọdun yi, nitoripe ọkan n i n u awọn l y i o m a ș e agbejọro ninu ęjọ yi ti ọ- we fun sisun ęjọ na siwaju

AKIYESI: Ko oro awon Oni Egbe Oofin t efe p r na aon Akint la ati Awo'ọwọ loju ewe kęfa.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT



# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI–OFE

ti o kun fun irohin aladun losose


**AKIYESI**

1 A nfẹ asoju ni awọn ilu wọnyi lo dan Oshogbo Ogbomosho Abeokuta Ile–Ifẹ Akurẹ Ilorin Iseyin Ọyọ Offa Awe ati Ede.

(2) A si tun nfẹ Ẹ ikẹni ti o ba mọ ... tabi itan O...yemọmọ ki o kọ iwe si OLOTU ELETI—OFE 28, Kosoko Street Lagos.

# Awọn Ọlọpa Mu Asiwaju Ẹgbẹ Alakuko Ijebu-Ode

IJẸBU—ODE:-Lori ijku oro to pa Ọmọba Odufunnade ti nṣe ọkan ninu awọn aṣiwaju ẹgbẹ Demo ni Ijẹbu-Ode ninu oṣu to koja ni a gbọ irohin pe awọn ọlọpa ti mu Ọmọba Hanfats Odukoya to jẹ ... fun ẹka ẹgbẹ Alakuko ni Ijẹbu Ode ni ọsẹ to koja.

Awọn ọlọpanu d...ẹ ati ọga wọn kan tijo njẹ Ganiyu Agbaje fun ipinlẹ Iwọ Orun ni Ibadan ni awọn lọ yẹ ile rẹ kan to wa ni opopo Molipa ni Ijẹbu ode wo fun ọpọlọpọ wakati ni irọlẹ ọjọ Abamẹta to koja lẹhinna ni nwọn ba mu lọ si ọgba awọn ọlọpa.

Ọrọ to ti ẹnu ọkan ninu awọn ọgaọlọpa si oniwe irohin kan ni ọjọ na ni pe hun to jẹ ki awọn mu Odukoya ni nitori ọrọ kan ti awọn kan ti nwọn ti mu ṣiwaju ka mọ o lẹsẹ lori iku ọmọba Odufunnade, ati pe iwadi si nlọ nipa rẹ.

# Eleti-Ofe D'araba

# Ẹgberun Pọnun Poora Ẹleri Fẹleri Su Ni Kotu

YABA—Ọmọge kan to nṣe akọwe owo ni Afrika Continental Bank, Adesọla Oluyinka Odujirin sọ ninu kotu ada ọ ke ere to wa ni Yaba ni Ọjọ Bo to koja pe on fura si eleri kan ti awọn ọlọpa pe ẹniti orukọ rẹ njẹ Sanday Akande Arowolo lori ẹgbẹ ... ẹgbẹrun pọnun ni iwe owo (£1,000 Money Order) nitoripe larin ọjọ meji si ara wọn eni ... na wa fi ẹdẹgbẹta pọnun din mẹfa (£454) pamọ si bani ti on gbe nṣiṣẹ.

Odujinrin tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe nigbati on bi Arowolo lere ibiti o gbe ti rowo nla bẹ yẹu, gẹgẹbi o ti ṣe ọmọde to, o dahun pe baba on to wa ni ilẹ Ariwa lo fi ranṣẹ si on, ọrọ wọnyi ni Odujinrin sọ nigbati o njẹri fun awọn ọlọpa ninu ẹsun mọkanla ti awọn ọlọpa ... si Ọmọba Adeniyi Oye an, Michael Adecisi Bẹwaji ati Sunday Edos fun idimọpọ, yiyi orukọ pada, yiyi iwe ati ... ẹgbẹrun pọnun eyiti o jẹ ti ọga oludari iṣẹ ... awọn oniwaya (P&T) ... ninu wọn, Sunny Ọmọ Edos ni o nṣẹwọn lọwọ fun ẹsun miran.

A ọwe baxxi na tun ni, ni ọjọ kọkanla aṣu kẹsan ọdun to koja, ọmọ ke'ere ... an ... ọmọ ọduu mọ anla lo kọkọ gbe iwe owo ti iye rẹ jẹ ẹdẹgbẹrun pọnun din ladọta wa siwaju on fuu fifi pamọ ṣugbọn on da pada nitoripe nwọn o ... lọ ... to ... ṣugbọn nikẹhin o tun gbe iwe owo ... orukọ Arowolo.

Ni ọjọ keji, o tun gbe iwe owo miran wa fun pọnun mẹrin–lerugba, ati pe ni kotu yi, Adebisi Bẹwaji wa nibẹ, bẹ na si ọmọge Moti... to tun jẹ asanwo ni bani kanna tun sọ pe larin ọjọ mẹrin Akande ti ni owo nipamọ o si gba okolerugba pọnun o din marun (£215) ni igba mẹta. Awọn Ọlọpa si nba ọrọ na lọ.



# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LEJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 938 SATURDAY Sept. 12—Sept. 18 1964

## Oro Olotu:

# Egbe Alamojuto Ire Eko

Ọrọ ni n' o mo ko, mo ro w ; ibere ọrọ kan ti ọkan ninu awọn ọkawe wa Ọgbẹni Lawale ni Ebute-Mẹtta bere nipa ẹgbẹ kan ti nwọn npe ni ẸGBẸ ALAMOJUTO IRE EKO (Lago sCitizens Rigbhts Protection Council) ti al gba wa, Oloye Ọlọla Adebayọ Doherty fi igba an da silẹ, wipe ṣe ẹgbẹ na tun wa tabi o ti paiẹ, ni o jẹ ki a kowe oke yi.

A fẹ ki ẹnyin ọkawe wa ti ẹ jẹ ọmọ Eko ti ẹ wa nile ati lẹhin odi mọ wipe Ẹgbẹ Alamojuto Ire Eko na si wa sibẹsibẹ, bi o tilẹ jẹ wipe awọn ti nwọn jẹ baba-sale ẹgbẹ na ko pariwo iṣẹ ribiribi ti nwọn nṣe fun ilọsiwaju awọn eto ara ilu E o

Kiṣe ti ẹnu, ẹnikeni ti o ba mọ Baba-isalẹ ẹgbẹ na, Oloye 'Bayọ Doherty lati igbati ti o nṣe aṣoju fun awọn ara Eko ninu ile igbimọ awọn aṣofin lati iwọn nkan bi ọgbọn ọdnn sẹhin yio mọ wipe ko sigi meji Obi ninu igbo ni ọrọ rẹ.

Ọlọla na ni ẹmi asapẹ; mimi sẹhin agbo tirẹ kiṣe tojo rara. Bi o ba mu ọrọ ire kan lọwọ lati ṣe fun ilu yio mu pari ni. O si fi iwa a nṣe rere yi jọ baba re Ologbe Josiah Henryson Doherty baba o n i n u re. Gbogbo wa ti a jẹ ọdọ nigba aiye rẹ ni a mọ bi Ologbe Doherty tiṣe fun alejo, ti o si ṣe fun onile.

Gẹgẹbi ọkawe wa Ọgbẹni Lawale ti wi, o ni awa Yoruba feran nkan ọfẹ pupọ. Bi awa na ko ba fe ṣe ọrọ egbe na ri ọrọ ọbẹ tutu tan adamu nfala, o yẹki a ran enito da ẹgbẹ na sile lọwọ fun ire awọn ọmọ ọmọ wa ti mbọ. Diẹ ni ọrọ Alaba ninu ọrọ Ibeji.



Oloye J. A. Doherty

# Iwe Si Olotu

# Egbe Ire Ilu Eko

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati kansara fun yin fun ọrọ isiri ti ẹ ko nipa awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọfin ti nwọn d de s ọrọ ọba Ile Ifẹ ti awọn ar du iẹ mba ja i ipa ọrọ [ ẹ ko kan ti nwọn si pari ọrọ na lọg n fun wọn. A dupẹ lọwọ wọn, nwọn ṣe pupọ A si tun gbọ wipe awọ ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn tun dide si ọrọ awọn Oloye marun ti Eko ti nwọn ti mba Ọba Adele ja.

Ẹ jọwọ ẹ la ọrọ na ye wa, ṣe ẹgbẹ na jẹ ọka fun ẹgbẹ Akọya fun ara Eko Lagos Citizen ti Ọlọla B yọ Doherty fi igba kan da silẹ ni? A ko gbo irohin awọn ọmọ ẹgbẹ akọya fun ara Eko na mọ kinni ṣe? Bẹ a gbọ wipe Ọlọla Baye Doherty nawo nara lori ẹgbẹ na akọ iya fun awọn ọmọ Eko.

Ọrọ awa Yoruba kọ mi lẹnu rara, nkan Ọlọfẹ ni a ma nfẹ, awa ki fẹ nkan ti yio mu owo jade lapo wa rara, afi ki nwọn ti ṣe silẹ ki a ma fi ṣe ifaa jẹ.

Ẹ jọwọ Olotu, ẹ tubọ ma ba wa tẹ mọ awọn agbalagba wa na leti ki awọn le ma tọ wa sọna ki a le ṣe ara wa lọkan.

Mo dupẹ lọwọ yin fun aye ti ẹ gba mi lati tẹ iwe yi jade.

Emi ni tiyin
A. Lawale

ỌRỌ OLOTU:

# Nipa Ofin Majekagbo

Ki odi ba gbọran ni a ṣe nsọ ọ leti ọmọ rẹ. Ofin tuntun ti Ijọba Apapọ ṣe fẹ gbe jade ni apejọ awọn aṣoju igbimọ aṣofin ti nwọn fẹ ṣe ninu oṣu yi, awa oniwe irohin pẹlu awọn ara ilu ni ofin MAJẸKAGBỌ bawi itoripe o dabi eni wipe nwọn fẹ fi ofin tuntun na di wa lẹnu ki a ma le sọ gbogbo nkan ti a ba ri fun ẹn in ara ilu mọ ni.

Gẹgẹbi iwe akọsiwaju kan ti a ri gba lati ile iṣẹ Ijọba Apapọṣe nipa ofin iwe irohin tuntun na, ẹnikẹni ti o ba jẹ Olotu iwe irohin ni ilu yi ko gbọdọ tẹ ẹda irohin tabi irohin agbaye nu kan ti o ba gbọ si inu iwe irohin rẹ. Olotu iwe irohin ti o ba tẹ ẹ jade yio fi ẹdẹgbẹfa pọnun (£500) gbadi pẹlu ẹwọn dun kan.

( Wo yoku loju ewe kejọ )

Eleti-Ofe D'araba

## Awọn Okunrin Meji Kan Nja Lori Ọmọ Kansoso

EKO – Tani o ni ikoko ọmọbinrin oṣu marun kan ti nwọn sọ ni oruko meji Temini Olufunmi Ogunsanya ati Bar kisu Abọsẹde Abiọdun Shonẹyẹ larin awọn ọkunrin meji kan? Ibere yi ni o mu iruju ba ile iṣẹ nibiti nwọn nkọ orukọ awọn ọmọ ti nwọn ba ṣẹṣẹ bi sile ni Eko ni ọjọ kokandinlọgbọn oṣu to koja gẹgẹbi iroyin ti a gbọ.

Awọn ọkunrin meji ti nja lori ọmọ kansoso yi ni Ọgbẹni Adebayo Ogunsanya ti o nṣiṣẹ ni ile iṣẹ awọn oniṣẹ ọlọkọ oju irin ti Naijiria ni Eko ati Ọgbẹni Olabọde Shonẹyẹ to nṣiṣẹ nile iṣẹ awọn oniṣẹ ni Apapa, lori ariyanjiyan yi si ni ọga agba ni ile iṣẹ iforukọ ọmọ bibi ati sisọ iṣẹ oku to ku si ṣe ranṣẹ si wọn pe ki onikaluku wọn ko iwe wa pẹlu alaye lati fi han bi on ni o ba ni ọmọ na larin ọsẹ meji.

A gbọ pe iya to bi ọmọ to daja sile na ti orukọ rẹ nje Yinka to nṣiṣẹ kọwe ni Eko yio wa siwaju awọn oluwadi ọrọ yi pẹlu awọn ọkunrin mejeji lati wa ṣalaye ibere wọn, ohun to si tu ọrọ yi sita ni wiwa ti Ọgbẹni Shonẹyẹ wa si ile iṣẹ iforukọ sile ni ọjọ kerindinlogun oṣu kẹrin ọdun yi pẹlu ọmọ na lati foruko rẹ sile.

Ṣugbọn akọwe to nforukọ sile sọfun Shonẹyẹ pe nkan na ko le ṣẹṣẹ nitoripe ọkunrin kan ti siwaju wa foruko ọmọ na sile gẹgẹbi Temini Ogunsanya, lẹhin ariyanjiyan diẹ, akọwe na ni ki Shonẹyẹ kọwe wa fun ibere lori ọmọ na, bakanna ni Ọgbẹni Ogunsanya.

Ninu iwe ẹbẹ kan ti Ogunsanya ti kọ siwaju pe on lo ni ọmọ, o sọ sibẹ wipe on gbe Yinka to jẹ iya ọmọ na ni iyawo gẹgẹbi aṣa ibilẹ ni nkan bi ọdun meji sẹhin, Yinka papa tun sọ ninu iwe tire to kọ ninu ọjọ kejidelogun oṣu karun ọdun yi pe ọkọ on keji ni on bi ọmọ na fun.

## Ole Pota Ji Bọmbu Gbe Lebute

PORT-HARCOURT:- Bọmbu Oloro ti nwọn le fi run ilu kan larin iṣẹju kan ni a gbọ irohin pe awọn ole kan ti wọn ko mọ nkan ti o jẹ ti jigbe pamọ si ibikan ni igboro ilu Ibo ni Port-Harcourt, ni ipinlẹ Ila Orun ti Naijiria.

Awọn Oyinbo awa epo, ti nwọn ni apoti bọmbu na ni ilukilu yowu ti nwọn ba gbe bọmbu na pamọ si yio di ilẹ bamubamu bi nwọn ba le daba lati si ọmọri apoti ibiti nwọn gbe gbe si wa lati ilu oyinbo nitoripe atẹgun majele ti npania wa ninu rẹ, awọn oyinbo ọlọkọ omi nla kan ni nwọn ṣe ifisuu yi ni Port-Harcourt ni ọsẹ to kọja.

Awọn aṣoju fun awọn Oyinbo ọlọkọ na nfi yeni bi o ti dun wọn to, nitoripe bi nwọn ba le ṣi ọmọri apoti rẹ kuro pẹnrẹn, ati ẹniti o wa nibẹ lojukanna ati gbogbo ilu agbegbe ibẹ ni yio parun raurau. Ẹnikan to jẹ alagbaṣọ fun awọn oyinbo ọlọkọ na ni awọn ko mọ ẹniti o ji apoti tabi ago ti nwọn fi gbe bọmbu na si lọ lati inu ọkọ oyinbo kan ti o duro seti erekusu ti nwọn npe ni Doms Island nitosi Port-Harcourt.

Aṣoju Alagbaṣọ na ni ago ti bọmbu na wa ninu rẹ wọn inṣi mẹtadinloguu ni fifẹ, inṣi mẹdọgbọn ni giguu ati ẹsun igba o din mẹwa ni wiwuwo (190lbs), o si tun sọ pe kini kan bi bọlu ti nwọn fi oje ṣe ti o tun ni ikoko irin kan ti nwọn fi bo atẹgun majele to wa ninu rẹ, pa, nwọn si sọ pe nwọn ma nlo iru bọmbu na fun gbigbẹ kanga epo lati inu ilẹ wa.

## Awọn Oloye Eko Tun Sinku Ọba Adele

EKO—Igbimọ awọn oloye Eko awọn ti Oloye Kofo Abayọmi ṣe aṣiwaju fun ni a gbọ wipe nwọn ṣe aaṣa isinku ikẹhin ni ọjọ Abameta to kọja ni iranti oloogbe Ọba Adeniji Adele Keji to waja gbogbo awọn ti Ọba na foye da lọla ni nwọn se aibẹ.

Agogo marun abọ irọle ni nwọn bẹrẹ eto isinku ikẹhin na dipo agogo marun ti nwọn ti lero tẹlẹ pe yio bẹrẹ, nigbati awọn ti nwọn fi iwe pe ati awọn ebi ọba ti joko saye wọn tan lẹhin na ni awọn oloye oni fila funfun bile wa tu jade lati inu Iga lati parapọ mọ awọn ti a fi oye da lọla pẹlu orin lọ awọn obinrin.

Awọn onilu sẹkẹrẹ ni aro ri ti nwọn ṣe nbẹ eyẹ ọjọ na nitorpe bi awọn oloye ti gbe esẹ kọkan ti nwọn si nja ohun ilu bẹni awọn fi owo ye onilu si. Awọn ti nwọn ko ijo mọra ninu awọn ti nwọn fi oye da lọla ni ọjọ na ni oloye Kofo Abayọmi, Baba Isale Eko, Oloye J. M. Johnson Minista eto awọn oṣiṣẹ



Dokita Majẹkodunmi

Oloye A. A. Ojikutu ati Alhaji Oloye Yẹkini Ojikutu, Balogun Eko.

Dide ti Oloye Dokita Majẹkodunmi, Mayegun Eko tise Minista tẹlẹ pa eto ile a ati ọlọla Adekunbọ Adeniọla Adelọgba fun ijọba apapọ ṣe ... desu agbo ni ... bẹrẹ ariwo si to kutu.

Ẹni ti o tun jẹ ... gbese ninu awọn oloye Eko lọjọ na ni Ọmọba Aminu Kosọko. Ash jọn ti o fi jo ... Gudu dara lọja na tọkẹ ... awọn enia fi patẹ ... lati gbadu jo rẹ.

Loni ọjọ Abameta ni awọn oloye pa ... ṣe aṣeyan isinku ... ninu Iga Idiganan.



Oloye Alhaji Ojikutu

## E Ka Oro Egbe Olofin to fe pari ija to wa larin Akintola ati Awolowo loju

Ewe Kefa iwe yi

## Awọn Okunrin Meji Kan Nja Lori Ọmọ Kansoso

EKO — Tani o ni ikoko ọmọbinrin oṣu marun kan ti nwọn sọ ni oruko meji Temini Olufunmi Ogunsanya ati Bar kisu Abọṣẹde Abiọdun Shoneye larin awọn ọkunrin meji kan? Ibere yi ni o mu iruju ba ile iṣẹ nibiti nwọn gbe nfi oruko awọn ọmọ ti nwọn ba ṣẹṣẹ bi silẹ ni Eko ni ọjọ kokandinlọgbọn oṣu to koja gẹgẹbi irohin ti a gbọ.

Awọn ọkunrin meji ti nwọn nja lori ọmọ kansoso yi ni Ọgbẹni Adebayọ Ogunsanya ti o nṣẹ ni ile iṣẹ awọn onilẹ̀ ọrọ Naijiria ni Eko ati Ọgbẹni Olabọde Shoneye to nṣiṣẹ nile iṣẹ awọn ... ni Apapa, lori ariyanjiyan yi ni oga agba ni ile iṣẹ iforukọ ọmọ bibi ati siso iye oku to ti ku silẹ se ranṣẹ si wọn pe ki onikaluku wọn ko iwe wa pẹlu alaye lati fi han bi on ni o ba ni ọmọ na larin ọsẹ meji.

A gbọ pe iya to bi ọmọ to daja sile na ti oruko rẹ njẹ Yinka to nṣẹ kọwe ni Eko ni o wa siwaju awọn oluwadi ọrọ yi pẹlu awọn ọkunrin mejeji lati wa ṣalaye ibere wọn, ohun to si tu ọrọ yi sita ni wiwa ti Ọgbẹni Shoneye wa si ile iṣẹ iforukọ silẹ ni ọjọ kerindinlogun oṣu kẹrin ọdun yi pẹlu ọmọ na lati forukọ rẹ silẹ.

Ṣugbọn akọwe to nforukọ silẹ sofun Shoneye pe nkan na ko le ṣẹṣẹ nitoripe ọkunrin kan ti ṣiwaju wa foruko ọmọ na sile gẹgẹbi Temini Ogunsanya, lẹhin ariyanjiyan diẹ, akọwe na ni ki Shoneye kọwe wa fun ibere lori ọmọ na, bakanna ni Ọgbẹni Ogunsanya.

Ninu iwe ebẹ kan ti Ogunsanya ti kọ siwaju pe o ... omọ, o sọ sibẹ wipe on gbe Yinka to jẹ iya ọmọ na ni iyawo gẹgẹbi aṣa ibilẹ ni nkan bi ọdun meje sẹhin, Yinka papa fun sọ ninu iwe tire to kọ ninu ọjọ kejidelogun oṣu karun ọdun yi pe ọkọ on keji ni on bi ọmọ na fun.

## Awọn Oloye Eko Tun Sinku Ọba Adele

EKO—Igbimọ awọn oloye Eko awọn ti Oloye Kofo Abayọmi ṣe aṣaaju fun ni a gbọ wipe nwọn se aṣa isinku ikẹhin ni ọjọ Abametta to koja ni iranti oloogbe Ọba Adeniji Adele Keji to waja gbogbo awọn ti Ọba na foye da lọla ni nwọn se sibẹ.

Agogo marun abọ irọlẹ ni nwọn bẹrẹ eto isinku ikẹhin na dipo agogo marun ti nwọn ti lero tele pe yio bẹrẹ, nigbati awọn ti nwọn fi iwe pe ati awọn ẹbi ọba ti joko siye wọn tan lẹhin na ni awọn oloye oni fila funfun bẹrẹ wa tu jade lati inu Iga lati pe rarọ mọ awọn ti a fi oye da lọla pẹlu orin ... awọn obinrin.

Awọn onilu sikẹrẹ ... aro ri ti nwọn sa nbẹ çyẹ ọjọ na nitoripe bi awọn oloye ti ngbe ese kọkan ti nwọn si njo ... ohun ilu bẹni nwọn fi owo ye onilu si. Awọn ti nwọn ko ijo mọra ninu awọn ti nwọn fi oye da lọla ni ọjọ na ni oloye Kofo Abayomi, Baba Isale Eko, Oloye J. M. Johnson Minisita eto awọn oṣiṣẹ



Dokita Majẹkodunmi



Oloye Alhaji Ojikutu

Oloye A. A. Ojikutu ati Alhaji Oloye Yẹkini Ojikutu, Balogun Eko

Dide ti Oloye Dokita Majẹkodunmi, Mayegun Eko tise Minisita ... pa eto ile a ati ọrẹ Adekunbọ Adeniọ a Adeọgba fun ijọba ap pọṣẹ ... desu agbo ni jo ta bẹrẹ awo si to kutu.

Eni ... jẹ ... gbese ninu awọn oloye Eko lọjọ ... Ọmọba Aminu Kosọko, Ash jọn ti o fi ijo ... dara loju na tọbe ... awọn enia fi pagbo ... lati gbadu jo rẹ.

Loni ọjọ Abameta ni awọn oloye pa ... ṣe aṣeyanri isinku ... ninu Iga Idiganran.

## Ole Pota Ji Bombu Gbe Lebute

PORT-HARCOURT:- Bọmbu Oloro ti nwọn le fi run ilu kan larin iṣẹju kan ni a gbọ irohin pe awọn ole kan ti wọn ko mo nkan ti o jẹ ti jigbe pamọ si ibikan ni igboro ilu Ibo ni Port-Harcourt, ni ipinlẹ Ila Orun ti Naijiria.

Awọn Oyinbo awa epo, ti nwọn ni apoti bọmbu na ni ilukilu yowu ti nwọn ba gbe bọmbu na pamọ si yio di ilẹ bamubamu bi nwọn ba le daba lati si ọmọri apoti ibiti nwọn gbe gbe si wa lati ilu oyinbo nitoripe atẹgun majele ti npania wa ninu rẹ, awọn oyinbo ọlọkọ omi nla kan ni nwọn ṣe ifisuu yi ni Port-Harcourt ni ọsẹ to koja.

Awọn aṣoju fun awọn Oyiubo ọlọkọ na nfi yeni bi o ti dun wọn to, nitoripe bi nwọn ba le ṣi ọmọri apoti rẹ kuro penrẹn, ati enini o wa nibẹ loju kanna ati gbogbo ilu agbegbe ibẹ ni yio parun raurau. Ẹnikan to jẹ alagbaso fun awọn oyinbo ọlọkọ na ni awọn ko mọ ẹniti o ji apoti tabi ago ti nwọn fi gbe bọmbu na si lọ lati inu ọkọ oyinbo kan ti o duro seti erekusu ti nwọn npe ni Doms Island nitosi Port-Harcourt.

Aṣoju Alagbaso na ni ago ti bọmbu na wa ninu rẹ wọn inṣi mẹtadinloguu ni fifẹ, inṣi mẹdọgbọn ni giguu ati ẹsun igba o din mẹwa ni wiwuwo (190lbs), o si tun sọ pe kini kan bi bọlu ti nwọn fi oje ṣe ti o tun ni ikoko irin kan ti nwọn fi bo atẹgun majele to wa ninu rẹ, pa, nwọn si sọ pe nwọn ma nlo iru bọmbu na fun gbigbẹ kanga epo lati inu ilẹ wa.

## E Ka Oro Egbe Olofin to fe pari ija to wa larin Akintola ati Awolowo loju Ewe Kefa iwe yi

Ewe Kefa iwe yi

# Egbe Omo Olofin Fe Pari Ija Awolowo Ati Akintola

EKO—Adajọ agba fun ijoba apapọṣe ti ilẹ Naijirja Oloye Adetokunbọ Ademọla sọ nib ipade pataki kan ṣiṣu awọn oloye ifu Eko nj Iga Idunganran ni Ọjọ Bọ to koja, nigbati o ti awọn oloye marun ti ijọba ti gba oye wọn lọwọ wọn lati nkan bi ọdun meji Sẹhin han awọn oloye miran wipe ija ọdun meji to ti wa laria Oloye Obafẹmi Awolọwọ, aṣiwaju ẹgbẹ ọlọpẹ atj igbakeji rẹ, Oloye Ladoke Akintọla ti nṣe olotu ipinlẹ Iwọ Orun lọwọlọw yio pari laipẹ.

Awọn oloye marun na ni Oloye Amisu Kosoko, Oloye Sikmi Akinyele, Oloye Tijani Bnlola Oloye Akanbi ati Oloye David Ogunlana, ẹniti ijọba yọ kuro loye lori ede-aiyede kan to ti wa laria wọn pẹlu ologbe Ọba Adele to waja.

Oloye Ademọla to jẹ Babasalẹ ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin tun sọ ninu ipade na pe ẹgbẹ on ti ṣe iṣẹ ribiribi pupọ ni pipari rogbodiyan to ti ṣẹlẹ nipa iṣelu ni ipinlẹ Iwọ Orun ṣugbọn awọn oṣelu ko jẹki iṣẹ imu nirẹpọ ti awọn ṣe yọ, nipa bayi awọn ti ilaja awọ ninu rẹ nireti pe ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin lodi si pipari ija ti o ba ba ti iṣẹ oṣelu lọ.

Ninu esi rẹ si ibere oniwe irohin kan o ni pataki ero ẹgbẹ Ọlọfin ni lati mu wa oju rere ati alafia fun awọn Ọba ati Ijoye ilẹ Yoruba ati lori itere nipa gige owo awọn Ọba ku si kọbọ kan lodun o dahun pe iru ipinnu bayi ti awọn Kansulu nṣe fun iwa bẹ kolẹ tu irun kan lara awọn Ọba.

Kete ti Oloye Ademọla pari ọrọ rẹ tan ọgbẹni S. Lana to nṣe akọwe Olotu Ijọba Apapọṣe ni "Mo ro pe o jẹ nkan to ṣe pataki lati sọ fun yin pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti pa aṣẹ kan pe gbogbo awọn Kansulu igberiko ko gbọdọ dasi ọrọ to ba ti ba ti awọn Ọba lẹ mọ, nwọn nilati fi iru ọrọ bẹ si abẹ aṣẹ awọn olotu"

Dokita Koye Majẹkodun mi ti nṣe alaga igbimọ ajiroro ẹgbẹ Ọmọ Olofin dahun si ibere kan pe Ẹgbẹ ko jẹ tun lọwọ si ọrọkọrọ kan to ba jẹ ti awọn Ọba lori iṣẹ oṣelu, bẹni lori ọrọ Ọba Iṣẹyin ti nwọn yọ kuro loye, Oloye Ademọla nj ẹjọ ti Ọba Iṣẹyin jẹ ẹniti o fara mọ ti oṣelu nipa bayi awọn ko lẹnu lati sọ si, didarijẹ Aseyin na wa lọwọ ijọba ipinlẹ Iwọ Orun.



Oloye Samuel Ladoke Akintola

Wo oju ewe karun lori

## Awọn Okunrin Meji Kan 'Nja Lori Omo Kansoso

OGBOMOSHO — Oloye Iyaafin Faderera Akintọla ti o tun jẹ aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ fun ẹka ti awọn obinrin sọ ninu ikede ẹgbẹ kan to ọ ṣe nj Ogbomọshọ laipẹ yi pe on ti kesi ijọba Apapọṣe ati ti ipinlẹ Iwọ Orun lati da eto nipa ẹkọ ọfẹ silẹ ki awọn obinrin ilẹ Naijiria le nj anfani ti ni ẹkọ iṣẹ iṣiwaju ninu ile ẹkọ Unifasiti to nbẹ ni ilẹ Naijiria.

Ninu ipade ikede ẹgbẹ to bi awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ṣe nj Ogbomosho, ilu ọkọ rẹ o ni ni ṣakiyesi pe ẹgbẹ ajumọṣe ti nwọn ṣẹṣẹ da silẹ pẹlu ẹgbẹ Dẹmọ ni o ma mu ki ijọba ipinlẹ Iwọ Orun lowo -lọwọ ati lati wa alafia fun gbogbo eniá.

Iyaafin Faderera tun tẹnu mọ bi ẹkọ nipa iṣẹ ọwọ obinrin ati itọju ile, ti ṣe jẹ nkan pataki fun awọn obinrin, o si ti kesi ijọba apapọṣe lati pese iru ẹkọ bawọnyi kakiri inu awọn ile-ẹkọ Unifasiti, ki awọn iran obinrin miran ti ni ọ awọn ti nwọn yio tun ilu ṣe lọhin ọla le ni anfani ati tun ilu wa yi ṣe.

Nigbati o nsọrọ lori ile iwe ọfẹ ni ipinlẹ Iwọ orun, ati iṣẹ afiṣe pẹlu bi awọn ti nṣe nj ilẹ Ibo, njbiti awọn tiṣa gbe ndaṣẹsilẹ ngbakugba lori aiṣedede owo oṣu wọn o ni eto to dara nipa ile iwe ọfẹ ti wa labẹ ijọba ẹgbẹ Dẹmọ nj Iwọ Orun o si ti nlọ daradara.

# Nine New British Aircraft On Display

LONDON — Nine of Britain's new civil and Military aircraft were on display to the World's aviation experts at the opining yesterday of the Farnborough Air Show, in Hampshire.

Altogether 26 different types of aircrafts are taking part in the flying display, and a further 15 types will be in the static exhibition.

Ten thousand overseas visitors are expected to be among the 250,000 people likely to attend the show before it closes on September 13.

New civil aireliners flying in the programme include the 'bus stop' B.A.C. 1-11, the Super VC. 10 to long-range jet, and the Hawker – siddeley Trident.

Westland Aircraft are demonstrating a 20 passenger, 70 knot Hovercraft, the S.R.N. 5. Powered by a 903 h p turbine engine, the craft is 38 feet long and can carry two tons of cargo instead of passengers. Its range is more than 200 miles.

Included in the static exhibition is a half scale model of Britain's satellite, the U.K 3.

## World's Quietest Room From Air Condition

LONDON — The world's quietest room air conditioner is claimed to be one of the exhibits at second International Refrigeration Fair, which opened Yesterday in London and continues until September, 11.

The conditioner, which cools or heats the air, reduces the humidity and filters out dust, is sound proofed with thick absorbent acoustic insulation. It has been designed in Britain to operate in high ambient temperatures. The makers Temperature Ltd., of London

# Apprentices' Hovercraft



Peter Hide, an apprentice at the aviation training school of the English Electric Company, demonstrates a one man hovercraft with which he and 17 other apprentices designed and built as exercise.

The machine, which floats just off the ground on a cushion of air is five feet in diameter, and is powered by a 500 cubic centimetre twin cylinder engine.

Read

and

advertise

In ELETI-OFE

Your Weekly

News Paper